# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO 866 TUESDAY DECEMBER 8, 1964 (2D)


## Awokoya Kilo Fun Awon Ọmọ Ile-Ẹkọ Lori Eto Ọrọ Ọṣelu

EKO:- Akọwe agba fun ile iṣe Minista Alamojuto eto ẹkọ fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati oludamọran lori eto ẹkọ fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Oloye S. O. Awokọya Ṣe Ikilọ fun awọn Ọmọ ile ẹkọ ati pe ọr awọn Oluko ile ẹko lati kilọ fun awọn ọmọ Ile ẹkọ pe ki nwọn ma ni owo ninu eto ọrọ Oṣelu tabi ki nwọn fi ẹgbẹ Oṣelu kan ma kọrin eyi to ba e ebu lọ.

Oloye Awokọya tun se alaye pe ọpọlọpọ awon ọmọ ile ẹkọ lo jẹ pe nwọn ma k'ẹgbẹ tabi ki nwọn ma kọrin eyiti Oloye Awokọya sọ pe ko ba oju mu rara ati pe kI iṣe ọna ẹtọ lati ma ri awọn ọmọ to ba fẹ jẹ ọmọ rere lati ma hu iru iwa bayi lori eto ọrọ Oṣelu.

Oloye Awkoya tun se alaye pe eleyi yio mu ohun to lewu pupọ wa fun awọn ọm ile ẹkọ ki nwọn ma da si eto Oselu tabi ki nwọn si ma se ẹyẹ ipolowo ibo eyiti Oloye Awokọya si rọ awọn oluko lati se ọna lati fi opin si iru iwa bayi ki awọn ọmọ ile ẹkọ le tete fi opin si iru iwa ti ko tọna yi.

## Ti Ẹgbẹ UPGA Ba Gba Akoso Apapọ Ijọba

# IPINLẸ IWỌ ORUN BỌ SINU AIYE RERE

**Ninu irohin kan to de ọwọ wa lati ọwọ awọn ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA ni nwọn ti ṣe alaye pe ti ẹgbẹ wọn (UPGA) ba le gba akoso apapọ Ijọba ile Naijiria lẹhin idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria nwọn ni gbogbo olugbe ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria paapa julọ ilu Ibadan ti y o mọ pe gbogbo nkan yio si yi pada si gẹgebi o ṣe wa bayi ati pe awọn enia ipinlẹ na yio bọ sinu ogo aiye rere.**



Dokita M. I Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakukọ



**Oloye Obafẹmi Awolowo**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ninu irohin to de ọwọ wa lati ọwọ ẹgbẹ awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijria (UPGA) ni nwọn ti ṣe alaye pe eleyi jẹ ohun iyalẹnu lati ri gbọ lati ẹnu olori ẹgbẹ alalero ẹgbẹ Dẹmọ NNDP Oloye Samuel Ladoke Akintọla pe ẹgb ilọsiwaju ilẹ Naijiria ko si gbe oye wo I ti ri pe ko tọna pe ko si ninu awọn ọmọ ilẹ Ibadan ti o ye laye Minisita rara ni Ijọba apapọ ilẹ Naijiria.

Ẹgbẹ ilosiwaju Naijiria UPGA tun sọ ninu irohin wọn pe eleyi yio jẹ ohun to fa ọgbọn fun awọn enia to ba jẹ ọlọgbọn t bi amoye ninu awọn to ba mọ nipa eto ọrọ oṣelu pe nigbati ẹgbẹ Alakukọ bori ibo si Ile igbimọ asofin ti apapọ ijọba ilẹ Naijiria ni ipinlẹ Iwo Orun ninu ọdun 1954 wọn ni nkan to yẹki gbogbo enia mọ pe iru ogo ti ẹgbẹ na ṣe nigbana pe ọmọ ilu Ibadan lo jẹ pe nwọn si ṣe ogo tabi ipo na fun lasiko na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilosiwaju ile Naijiria UPGA tun ṣe alaye pe lẹsẹkẹsẹ ti nwọn gbọ abayọri eto idibo si ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria lasiko na ni awọn ẹgbẹ Alakukọ yana yan ọkan ninu awọn ọmọ ile Yoruba to je paraki ninu wọn gegebi Minista ninu apapọ Ijọba ile Naijiria eyi ti iṣe ologbe Alhaji Adegoke Adelabu ni awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ yan gegebi Minista ekini lasiko abayori ibo ti ọdun 1954.



Oloye S. L. Akintola
Olori ẹgbẹ Dẹmọ

Irohin lati ọwọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria na tun fi ye wa pe Oloye S. L. Akintola to jẹ pe awon ẹgbẹ Afenifere fi si ipo gegebi enia kan ti o ni lati mo lori bi eto alafia ilu Ibadan se nlo si lasiko ati gegebi Oludamọran fun ẹgbẹ Afẹnifẹre lori eto ilu Ibadan nigbana ni awon ọmọ ẹgbẹ UPGA tun ṣe alaye pe ko si dun mọ awọn ninu gẹgebi ipo ti nwon yan Ologbe Alhaji Adelabu si lasiko na.

Irohin lati ọwọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria na tun ṣe alaye pe ki iṣe ohun to dun si Oloye Akintọla bi ko ṣe pe ọna to je pe yio ṣe yọ Ologbe Alhaji Adelabu kuro lori ipo to wa ni asiko na lo si njadu ọna ti on yio si gba ṣe jamba na fun.

RIKIṢI

Ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA tun ṣe alaye ninu irohin wọn pe on kanna ti iṣe Oloye Samuel Ladoke Akintọla lo ba awọn ẹgbẹ enia bi Oloye A. M. A. Akinloye Padipọ eyi to jẹ pe rikiṣi lo pa wọn pọ nigbana ti nwọn si ditẹ pọ ti nwọn tu ile igbimọ ti ijọba ibilẹ ti ilu Ibadan ka nigbana lori pe awọn ọmọ ile igbimọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ibadan na si nko owo ti Ijọba ibilẹ na jẹ eyi ti nwọn si fi ditẹ si awọn ọmọ ile igbimọ Ijọba ibilẹ na ti nwọn tu ka eyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA si ṣe alaye pe lori agbara ti ẹgbẹ Afenifẹre nṣe akoso rẹ nigbana ni nwọn ditẹ lati lo agbara na lori wọn.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA tun ṣe alaye ninu irohin wọn pe nigbati nwọn yọ Ologbe Alhaji Adelabu kuro lori oye gẹgebi Minista fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria awọn ẹgbẹ Alakukọ si tun gbinyanju lati wa ọmọ ilu Ibadan miran lati fi rọpo rẹ gẹgebi Minista fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria lasiko na.

Ninu irohin na ni ẹgbẹ ilosiwaju ilẹ Naijiria ti ṣe alaye pe nigbati ẹgbẹ Alakukọ kuna lori eto eyi ni lati fi elomiran rọpo Alhaji Adelabu, nwọn ni ọdun keji na ni nwọn ṣe idibo si ile Igbimọ asofin ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyi to jẹ pe ẹgbẹ Alakukọ si kuna lati gba

WO OJU EWE KẸFA

# ỌRỌ OLOTU

## Njẹ Eleyi Fa Isọkan Si Ilẹ Naijiria

Lati nkan bi ọsu kan ati ọse diẹ sẹhin ni a ti ngbọ ija Igboro to nṣẹlẹ ni ẹkun TIV, ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria eyi to jẹ pe ọpọlọpọ ẹmi lo ti padanu ninu ija to nṣẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu to wa ni Ipinlẹ Ariwa paapa julọ ẹkun TIV, ṣugbọn ohun to jẹ pe o tọ o si yẹ bayi ni ẹkun TIV ni eto ofin p a j a w iri eyi to yẹ ki Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria yẹ ki o ṣe eto rẹ bayi lati le fi ka ẹsẹ iwa bnburu to jẹ pe o nṣẹlẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu ti o wa ni ẹkun TIV

A ro pe nkan bi ọsẹ diẹ sẹhin ni Irohin fi ye wa pe awọn Ọ l ọ p a fi ara gbọgbẹ ninu awọn Ọlọpa ilẹ Naijiria eyi to jẹ pe awọn lo ni agbara ju ninu oriṣi meji Ọlọpa ti a ni, ni ilẹ Naijiria nitori eyi apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ṣe eto lati ko awọn ọmọ ogun ilẹ wa lọ si ẹkun TIV lati lati lọ ṣe eto bi ofin rere yio ṣe le tete pada si agbegbe na, ṣugbọn eleyi ko tun rọgbọ rara lẹhin ti awọn ọmọ ogun ilẹ Naijiria de agbegbe na.

Ṣugbọn ohun to jẹ pe Irohin Imọlẹ ro pe o ye lati ṣe ni eto ofin pajawiri, Nigba ti nwọn ko ti tu ile Igbimọ asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ka ti gbogbo nkan ṣe bayi orin ni orilẹ ede wa rẹ jẹ ti nwọn ba lọ tu ile igbimọ na ka bayi ohun ti yio ṣẹlẹ ni ipinlẹ na ko ha ni pọ ju bayi lọ bi?

Eleyi paapa fi han gbangba pe ipade ti awọn Olori ẹgbẹ oṣelu ilẹ Naijiria ṣe ni ọjọ ketalelogun osu yi eyi ti nwọn jijọ panu pọ ṣe adehun lori eto ibo to mbọ eyi ti nwọn ṣe adehun lati le jẹ ki eto ipolowo ibo lọ ni ọna ẹtọ laisi pe ija tabi rugbodiyan uṣelẹ larin awọn ọmọ ẹgbẹ oselu an pe ki nwọn fi ọlọpa Ijọba ibilẹ ni awọn ipinlẹ Naijiria ati ki o ma ṣe si pe awọn ẹgbẹ oṣelu kan ko gbọ dọ de lu kan ni awọn ipinlẹ Naijiria lati lọ ṣe ipade ipolowo ibo pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ni awọn ilu ni ilẹ Naijiria eyi ti gbogbo awọn Olori ẹgbẹ oselu jijọ fi ọmọ si iwe adehun naṣẹ na,

Ṣugbọn ohun to jẹ pe o ya Irohin Imọlẹ lenu ni eto ofin adehun na ni iru ọpọlọpọ iwa ti awọn Ijọba ibilẹ Ipinlẹ Iwọ Orun ati ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria hu lori eto adehun na ko ba oju mu rara ati pe eleyi yio mu nkan bi itiju wa fun awọn enia ilẹ Naijiria paapa julọ awọn Olori ilẹ wa ni ilu okere ohun to jẹ ki Irohin Imọlẹ sọ eleyi ni pe ọpọlọpọ ohun to nṣẹlẹ ni awọn ipinlẹ wonyi lo si jẹ ohun to buru pupọ ju lati ma ri pe olotu Ijọba Ipinlẹ Ila Orun ati Akele olori ẹgbẹ Afẹnifere lọ fun irin ajo ipolowo ibo si ipinlẹ Ariwa eyi to fi jẹ pe ọpọlọpọ awọn ilu ni nwọn de ti awọn Ijọba ibilẹ awọn ilu ni awọn ilu na ko gba wọn l'aye lati ba awọn ọmọ ẹgbẹ wọn sẹ ipade ṣugbọn eleyi Pẹlu nkan ti awọn olori ẹgbẹ oṣelu ile Naijiria se adehun le lasiko ipade ti awọn olori ẹgbẹ oṣelu na ṣe ni ọjọ ketalelogun osu kewa ọdun yi.

Nigbati uwọn dẹ ile itura ti Ijọba ipinlẹ Ariwa kọ ti awọn olori ẹgbẹ mejeji wọ yi pẹlu awọn ọmọ lẹhin wọn fẹ sun si ile itura na nṣe ni awọn ti nṣe akoso ile itura na kọ dele patapata ti nwọn ko fun awọn Olori ẹgbẹ na ni aye lati sun eyi ti nwọn ọgbọn eke se alaye fun awọn olori ẹgbẹ na pe ko si kankan ti nwọn le ri fun awọn olori ẹgbẹ na pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn.

Njẹ iru iwa bayi ha fa isọkan awọn enia ilẹ Naijiria bi ? eyi to jẹ pe igba gbogbo ni awọn olori ilẹ Naijiria nfẹ ẹnu kan pe ki awọn enia ilẹ Naijiria ni isowọpọ ki a le di ọkan ṣoṣo ṣugbọn ti iru eyi ko ba ni opin eleyi ko le fa isọkan wa fun awọn enia ilẹ Naijiria rara.

Ti a ba tun mu ẹnu ba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria a o si ri pe iru nkan to nṣele ni ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria na lo si nṣẹlẹ ni ipinlẹ na. nigbakan ni iyawo Olotu Ijọba ipinlẹ Ila Orun

Naijiria lọ fun eto ipolowo ibo si ipinlẹ Iwọ Orun ati iyawo Olori ẹgbe Afẹnifẹre eyi to jẹ pe awon Ijọba ibilẹ ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ko fun wọn ni aye lati gẹ eto ipadẹ ipolowo ibo pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ wọn Eyi to buru pupọ ju ni iwa ti Ijọba ibilẹ Ekiti hu si iyaafin Adanma Okpara eyi to jẹ pe ojo nro ti iyaafin Adanma Okpara ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ti nwọnjijọ nse eto ipade ipolowo ibo ti o jẹ pe nwọn ko fun wọn laye lati ṣa fun ojo ni ilu ejọ ti na eyi to jẹ pe nse ni nwọn bọs nu ojo na

Ẹnyin Olori ẹgbẹ oselu ilẹ Naijira ẹ tete lo rio inu nyin dada ki ẹ tete fi eto si iru iwa to nṣẹlẹ ni ipinlẹ na larin awọn ọmọ ile igbimọ asofin ti Ijọba ipinlẹ ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eleyi ko mu isọkan ba awọn enia ilẹ Naijiria Eleyi paapa ko mu ohun to fa wọnyi wa fun awọn ti ọmọ ilẹ Naijiria to wa ni ilu okere ti nwọn ba ngbọ iru nkan to nṣẹlẹ ni awọn ipinlẹ ilẹ Naijiria.



Aworan oke yi ni ti Oke Olumọ ni ilu Abẹokuta. Iya arugbo kan ngbe abẹ apata Olumọ, na iya na ti to ni ọgọrun Ọdun. Nigbati o ... a ni ẹni ogun ọdun lo ti ngbe abẹ Olumọ na.

# IWE SI OLOTU

## Omo Igbomina O di Owo Nyin

Olotu inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye die lati kesi awon omo iya mi ati elegbe mi ni ilu Eko ti nwon je omo oko ile Igbomina lati mo pe eto idibo to mbo yi je ibo ti o dabi pe nse ni awa enia le Naijiria nlo s'oju ogun pappa awa omo ile Igbomina.



Ogbeni J. S. Olawoyin

Awa Baba nyin atiegbon nyin to wa ni ile Igbomina ni idanilaju pe Ogeeni Olawoyin ati Hassani Balogun yio bori ibo to mbo yi lagbara Olorun. Sugbon nkan ti a nfe ki enyin enia wa to wa ni ilu Eko se bayi ni ki e gbinyanju lati wa si ile lati dibo fun awon omo egbe Afenifere meji yi ki a le bo loko eru egbe Olomi NPC, Nitori eyi o di owo nyin o.

Emi ni
Omupo Alfa Yinusa.

ni eye rampe die lati fi ye awon omo egbe Olomi NPC to wa ni ilu Eko ti nwon je omo ile Igbomina pe ki nwon lo si ile ki nwon lo mo pe awa Baba wa ati Egbon wa to wa ni ile ki ise ode oju won tila ko si nkankan to le mu wa se egbe Olomi NPC mo ni ile Igbomina awa si ti duro gbonigboni bayi pe ogbeni wa J. S. Olawoyin li nba lo ati pe ko si si ohun to le fa ti ko ni fi wole ibo to mbo yi to bo tile je ogba awon ni awa wa ti ogbeni Olawoyin ni awa yio ma se Nitori eyi egbe Olomi ti ku patapata ni ile Igbomina enikeni to ba ogbeni Olawoyin fi agagbaga Oluwa re yio padanu owo idibo re ni. Olotu mo dupe fun aye ti e gba mi.

Emi ni
Biola Akanbi
Eko

## Egbe Demo Ti Ku Ni ilu Ijebu - Ode

Olotu Inu mi yio dun bi e ba le gba mi ni aye die lati kesi awon omo ilu Ijebu - Ode ati agbegbe re lati fi ye awon agba jeunjeun pe egbe Demo ko fi igbaa kan wa ni ilu Ijebu-Ode atiegbe re. Eleyi si ti fi han pe egbe na ati awon agba iya to nse egbe na ni ilu Ijebu - Ode ti ku patapata.

Inu awa odo yio dun bi enyin agba na ba le tete lo ronu jinle ki e pada lehin egbe onikumo ki nwon tete pada sinu egbe Afenifere eyi to je pe on ni egbe ti omode ati awon agba ilu Ijebu - Ode mo ni e g b e to ni anfani to po l o w o lati fun awon enia ilu Ijebu - Ode ati agbegbe re. Olotu mo dupe pupo fun aye ti e gba mi.

Emi ni
A. B. Adesola
Ijebu - Ode

## Egbe Olomi Ti Ku Ni Igbomina

Olotu :- Jowo gba mi

## Mo Ti Ko Pa Oruko Mi Da

Mba so pe bi Olotu ba le gba mi laye die ninu iwe irohin oloyin momo tio kun fun ogbon ati oye lati ke si arajye gbo pe nko je oruko mi mo moti kuro ni Akintola mo ti di Akinola Nko dede sobe nigbati mo nri bi aiye ti fiya lo bi ogo orin awon ologbon Ni gbati gbogbo ara ile ati adugbo wa ba gbo oruko mi nwon aberesi sope were ni gbogbo awon Akintola ati gbogbo won ni won de buru nigbati moba sope ki soro won ama sope gbogbo aw iba uje ni eleyi nje nigbati moba ngbo

Nwon ama gbami lori won ama fi efun ikowe ko la simi la a won ako oie si mi lara Nko le ri n! adugbo wa mo ni osan ayafi ti ile basu nwou ni oruko ma ro nipe awon ni awon ma lu mi pa Mo ko ti jaiye rara ni torina ni mo se yi oruko Akintola si Akinola Olorun ko ur fi ya se temi o amin Akinola ni oruko Nko je Akintola mo.

Emi ni E Akinola

# EGBOGI JEDIJEDI

BERE BGBOGI



CYCLOVEN

Aworan egbe yi fihan gban gba ibiti Jedijedi re wa ni ara re ti nyoo lenu nigbagbogbo. Ibe ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma ngba se igbonse. Arun Jedijedi je okan ninu amodi ti o buru ni pataki fun okunrin ti o si soro pupo lati se iwosan re patapata.

Opolopo egbogi ni o wa ti a nta kakiri ode nisisiyi t nwon ni a npolowo nwo fun iwosan re sugbon boya ni a le i ri mewa ninu awon gun ti o le se iwosan arun re daradara. Awon elomiran lero wipe boya bi won gbe lo si ile iwosan lati lo ge eyiti o bi nyo jade omusu ku nipa be awon o bo lowo re patpaata.

Sugbon awa ko ro be rara lehin odun die iyonu re vio si tun bere bakana Orisirisi Jedijedi ni o wa Ekini ti o bere nipa aiko ma se igbose dede tabi lojojumo elomiran nipa ijoko ni ojukanna pupo ojojumo abi gigun keke ologere (Basikulu) pupo elomiran ewu eran Suga oniruru ohun adidun pupo, pupoju nigba kugba Jedijedi orisirisi ni o wa, ewo ni tire? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ba umu eje walehin igbonse tabi ti o ba nyo ti o ba se igbonse tan ni tabi ti nrin o ninu omusu ni eyikeyi ti o ba je bere egbogi CYCLOVEN ati awon Oyinbo Jamani sese wa idi re kio si danwo kuaju wipe iwo yio bo lowo Jedijedi patapata alafia yio de ba o ekeji re ko si ninu gbogbo awon ti a tanigboro Naijiria bere ni :

NIGERIA MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos
WATER-LOO MEDICINE STORE
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Oja
ATI NI SOBU
OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA
IBADAN.

# KERE O! Akiyesi Pataki

## Anootin Tablets ! Antion Tablets !!

Enyin Abiyamo lokunrin ati lobinrin, Mo ba yin yo E ku afojuba egbogi pataki ti a se iwadi re lati owo awon Ojogbon Onisegun (Specialist) Ilu Oyinbo.

Fun awon ajakale awon wonyi:--
IGBONA:- Eyi je Arun ti o sopo nisisiyi papa julo arun awon Omode ati Agbalagba.

ORI FIFO TULU LUKULUKU, OTUTU IGBA AIYA ARA RIRO ati OTUTU OREREN pelu AKOKORO Jowo danwo ajebidan ni ogun yi. Irohin ko to afojuba Bere iwe ti e o fi lo lowo eniti o ba ta Egbogi na fun nyin: O daju han-un, E o ri ise re lehin iseju medogun ti e lo. Bere lowo Onisegun adugbo re.

*Distributors:-*

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone;- 23745.
LAGSO

# YE IRAWO RE WO

AQARIUS (Jan 20-Feb 18) Ire ni ọjọ oni yi yio jẹ fun ọ fun imọran titun ti o ṣẹṣẹ gbe kalẹ. Rere ni oni jẹ bi ọrẹ ba wa ki ọ, tabi bi alejo kan iba wa ki ọ Gbogbo enia yio ma gbadun rẹ.

PISCES (Feb 19- Mar 20) Ọrẹ rẹ kan yio da ija silẹ ṣugbọn iwọ ko gbọdọ binu, nṣe ni ki o ṣe suru, ki o si bọwọ fun awọn agba iṣẹ rẹ yio ma lọ daradara, bi o ba di ọsan, ki o rin fẹaji lọ.

ARIES (Mar 21-April 19) Ori rẹ ati ọgbọn rẹ pe, ṣugbọn ki o ṣe pẹlẹpẹlẹ nigbati o ba fẹ lo ọgbọn na nṣe ni ki o kọkọ danwo maṣe binu abisodi.

TAURUS (April 20-May 20) Iṣẹ ati owo yio jẹ ṣiṣe ti lilo fun ọ. Iwọ yio tu aṣiri Obinrin kan wo, tọju nkan ti ara rẹ.

GEMINI (April 21-June 21) Awọn ẹmi Ọrun tako ọ lọna kọna, ijo ati erọ ṣiṣe rẹ yio mu itẹlọrun wa.

CENCER (June 22-July 22) Ọjọ ire lọjọ oni ọpọlọpọ ọrọ li ati yanju ṣugbọn maṣe huwa, nṣe ni ki o ni ọrẹ titun.

LEO (July 23-Aug 22) Ọjọ ire lọjọ oni oni, lọnakọna ọwọ rẹ yio tẹ owo tabua ṣọ awọn ọja ti o ni lati ra loni ohun ti o tọ ni ki o si ra.

VIRGO (Aug 22-Sept 22) Awọn iṣoro kekeke ti o mbẹ loju ọna rẹ ni iwọ yio ṣẹgun rẹ. Ṣugbọn maṣe jẹki nkan miran tun fa ọkan rẹ sẹhin, lọ ki o lọ ki awọn ọrẹ rẹ loni ninu ile wọn.

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Bi o ba sẹ sọrọ owo, o ni lati lo ọgbọn ori ki o maṣe ṣe kẹta, maṣe sọrọ ti yio mu ipade ibinu ki o si ṣe jẹjẹ nibi iṣẹ rẹ.

SCORPIO (Oct 24- Nov 22) Lo egbogi awure rẹ iwọ yio si ṣorire jaburata. Iṣẹ yio ma lọ siwaju adehun yio si wọ ara wọn.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Kuku ṣe gẹgẹbi o ti nṣe latijọ nigbati o mbẹ lẹnu iṣẹ ki o ba le bọ lọwọ ijọngbọn alejo kan ati kuro lọwọ Obinrin gbajumọ kan.

CAPRICORN (Dec 22 - Jau 19) Bi o ba jẹ pe oju rẹ ko le kuro ninu ohun gbogbo, owo yio ṣọwọn fun ọ fun igba diẹ, Maṣe tete ma bẹ lu ọrọ ki ọrọ ara rẹ ba le ma lọ geregere.

---

# Owe Yoruba

Lati Ọwọ Omidan Falilatu Areago

1, Werepe ko ni ibi kan ti agbamu, gbogbo ara ni ifi joni.
2. Ọlọgbọn ko ni tẹ a r a rẹ n'fa ọmọran kofi' ra rẹ joye; ọbẹ to' mu ki igbẹ eku ara rẹ.
3. Ṣe ki ngfi idi hẹẹ? n i afomọ fi di onile
4. Ọtun wẹ osi, wẹ ọtun ni ọwọ fi mọ.
5. Ọbaiyejẹ ko fi idi oran ọrọ hau.
6. Odo to toju ẹni kun, ki igbe ni lọ.
7, Abiku ṣọ ologun de ke
8. Aki iki ago fun fun ẹlẹsin ana.
9. Aṣọro wo bi arun idile.
10. Bi ajanaku ko yo igbẹ ni oju yio ti.
11. Bi ako ba riAdọn a f i Adẹ ṣẹbọ.
12. Elete ko pa a l'oju ẹni ẹhin ẹni la gbimọran ika.
13. Ẹniti a mba pete a t i ra ẹṣin ni ifẹ sọ nidi oloko ẹṣin.
14. Bi alẹ ko tẹ adọn ki ifi.
15. Ẹniti oba ma jẹ oyin inu epala ko ni woju ake
16. Ẹmi abata ni imu odo ṣan, ọla baba ni imu ọmọ yọn.
17 Ẹniti alu l'ogbo mẹfa ti ani ki ofiyedenu, igbati ko ni fiyedenu nkọ.
18 Ikoko titun ma le garan wo, ho pẹ titi onpada nbọwa di ifọna.
19. Ṣiṣe silẹ ni abọwa wa ba, ẹni to ṣu sọna a ba eṣinṣin ni gba aṣọ.
20 Ohun to ṣe agbigbo to fi dẹ kun ẹrin, b'oṣe gunnugun awonkoko sori ẹyin
21. Bi aiye ba nyẹ w ọ n , Iwa ibajẹ ni nwọn ma nhu, o nfa fun alapata to ni on a fun Ẹkun l'Eṣin Ẹwuẹjẹ ki yio wọ.
22. Nitori aditi ojo ṣe nṣu, nitori afọju ni ojo ṣe nku.
23. Ẹniti o gbọ ifa ko mọ Offa ẹniti o mọ Offa ko gbọ ifa, bẹni Ifa, ta l'Offa
24. Ajanaku ki sọ' pa ki' nu o bi Ọlọdẹ,
25. Orule bo aja mọ'lẹ, awọ, tẹrẹ bo' nu ko jẹ ki a ri' kun aṣeni.
26. Arun t'o ṣọgoji l'o Aboyade gbogbo Ọyọya lu nṣe.

---

BI ARA RẸ SILẸ PATAPATA LỌWỌ IKỌ BU BURU GBOGBO NIPA LILO EGBOGI:—

## RCHALET

dajitirọ. Iṣẹ re lara Kan fun Iwosan gbogbo kokoro buburu t o bi ko

FUN ARUN ẸJẸ ninu, ẸJẸ ARA bi Mọnamọ-ARA BIA GBOGBO

Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta Kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn ṣe ewọ, a wa ki ta awọn egbo i ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npe ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onbiara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba mọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani Faranse ati awọn Tatambulu si Itali jẹ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ arb ko ba mọ daradara awọn amodiagbe ailera wọnyi le ṣe ọ Lukulaku orişirişi Inaru, O j u ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Ako ibu arun Ẹdọki, Aya didun pupọ ati Ekur laya.

Ara riro. lapalapa,Egbo-ṣẹẹ modi Apo ile itọ, ẹnin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ rẹ patapata yio si fọ ẹjẹ mọ to nitoni pelu.

Ṣa dan igo le kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu. PRICE 13/6d postage 36/




WATERLOO MEDICINE STORES
Palm church Street, Lagos

---

GBỌGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK

AE-BI-ALE Egbogi tọniki Jamanu titun ti kbogbo ara ilu Eko ati Jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbid an iṣẹ rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ko ba ṣiṣẹ daradara ti Eemi Breath) inu rẹ ko ba gunlẹ daradara fun iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo' tabi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun o si de adọrin tab ubẹ lọ. Mọ daju pe "DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ'ara rẹ di ọtun pa tapata ara rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ tio ti hunjọ yio yi po pada patapata alafia ati gbadun yio de si ọ Iyẹn bẹ.



Bere egbogi na ni Ṣọbu:
MIGERIAN MEDICENE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, (Ọja Ita Faji
Lagos, Nigeria.
ADEDUN CHEMIST
14 Wakeman Street Yaba

# AWOLOWO D'ORIṢA ( Apa Kẹjọ )

## Ẹ Tuju Ka Ẹnyin Ọmọ Ẹgbẹ Awolọwọ

Mo ki Oluwa mi tesoteso, mo ki i tologuntologun Nko da awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ si. mo sọ fun yin: "Ẹ tuju ka Ẹnyin ni ọmọ ẹgbẹ aifoya ati ọla.

### Lati Ọwọ ADIO MOSANYA



**Oloye Obafẹmi Awolowo**
Ol ri Ẹgbẹ Afẹni ẹre

'M foya ra m f' ẹs ko
Bi ọ a re ilẹ dudu bi oru,
Irawọ a w to t to or rẹ
ilẹ lẹ s' n ;
Gb kẹle Ol run ki o si ṣe
rere

Ko si ohun t tun kan li aiye yi larin igbona ogun ni adoju ibọn ko Napoleon Bonaprte. Ota ibọn na ni iba ba Napoleon lẹsẹkẹsẹ ṣugbọn ọm gun re kan. ti o ma pe il Franse Tko le ri irn Napoleon mọ, fi ara re di Napoleon l' oju Nipo ṣiṣe be, o gba Napoleon la ati ogo ile Franse O ku ọla, a si sin pelu ogo Orukọ rẹ ko si le parun, Kini iwọ ṣe lati gba Ogo ile Baba rẹ la ki a si fi wu ra ko oruko rẹ sinu iwe itan.

Ko si eniti o le pa ayan mọ da-iba se iku, tabi inilara tabi Ile ni kuro ni ilu Herodu Nl g a ọna eburu g' ori itẹ o jọb ni ekun, o si ku bi aja Oliver Cromwell pẹlu iranlọwọ awọn ọmọ ogun rẹ, pe oba Charles Ekini ti ilẹ Gẹsi lori ṣugbọn nigbati ẹsan de bi o tilẹ je pe o ti ku nigbana nwọn wu egungun oku rẹ jade Nwọn pee l'ẹjọ nwọn si gbe egungun pe ko igi wọn yẹ igi mọ lẹsẹ loju gbogbo enia Eyi fihan gbangba ohun ti awọn iran ti mbọ le ṣe lati tun ohun ti o ti wo ṣe Ohunkohun ti le jẹ ṣ se iran yi, atun ṣe yio wa lẹhin ọla a o si ko wọn silẹ ninu iwe itan

"Emi iba ni orogun ahan Orogun ẹnu Ati ohun irin ng ko le f' ẹnu so gbogbo ẹsẹ Yoruba tan abi ki ng sọ iya ti Yoruba fi nje alaiṣẹ

Nitori nigbati ọgbẹni Aminu Kano sẹ apon ninu ile igbimọ Asofin ajosepo pe ki a ma f' oju fo ohun ti Awolọwọ ti sẹ fun ilosiwaju ile Naijiria awọn Yoruba olorinla ngbero bi wọn yio sẹ yi oruka Ọja ti a fi da ọruko Awolow lọla pada si omiran "Bi ikorira doju iku ati on nikẹhin."

### ỌRỌ AKỌ LATI ENU AWOLOWO

Nje enikeni tun wa ti o nṣe iye meji bi Awolowo je akoni ati orisa akunlebọ? Jẹki eni na ka oro igbehin ti Awolowo so ki adajọ Sowemimo to ju s' ewọn odun mẹwa. Awo so bayi pe.

Mo ki adajọmo fe so oro die ki o t da ejo mi (ju mi s' ewọn) pelu iteriba ni mo ni lati so fun o po eyo yi le de iwaju kotu ti o gaju tire lo nitoripe nko fi ara mo gbogbo ohun ti o rọmọ gba gbo ti o fi da mi l' ejọ fun bi ogbọn ọdu n ninu igbesi aiye mi mo ti nṣe iselu Naijiria ko si ohun ti ko sẹ ni ile Naigiria wa yi ni gbogbo asikoyi pelu awọn oṣelu ẹgbe mi mo ba awọn Gesi fira a si gbe awọn enia dudu si ipo ti nwọn ko lero pe awọn le ni okan bi ogun ọdun si ode oni.

**Adura Jẹ J'ogun Lọ**

| | |
|---|---|
| A ti ni Iwe Adura patiki fun Asiki lati Musira | 2/6 |
| Iwe Adura Akanṣe ati apẹrẹ ile aiye | 2/- |
| Iwe Itumọ Ala ati Adura Ala ibanujẹ | 3/6 |
| Iwe Afọmọ-isin Ojiṣenia Muhammed | 1/6 |

Bere tabi F'owo ranṣẹ si :—
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue, Lagos Nigeria
Ni eti Ọja Jankara.

**Congreves Female Remedy**
(FUN OBINRIN

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amo di inu ririn nigbakugba tabi ni ẹkọ ọkan ẹhin didun ibadi wiwo tabi sisan ẹjẹduu ati tabi aikoto ẹlẹ ara Inu gbigbona nigbakugba Igba-aiye riro ọmu riro didun arẹ atinu wa ni o ma nfa oyi-oju llaogun a a ẹṣẹ ara sisan ẹfori tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itoju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orisirisi amodi miran ti o ma ayọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu
(OLOMI IGO NLA NI)
BERE EGBOGI AJỌ WỌN NPENI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba laila k wọn Orisirisi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to ada tiawọn agbalagba aiye atijọ mn ati wipe ko si ohuukul ale fi iwe egbogi yi bi otutu ikọ, iba, orẹrẹ lauduku onibamaji ti aiperi n yọ enia lẹnu yala Ọmbe tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oa ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọn eti riro tabi se iwosan iyọnnu apo ile-ito egbogi oju didun tabi ni ọna-ọfun didun, ati orisirisi omiran pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn:-

NIGERIA - MEDICINE STORE
4, Tinubu Sqare Lagos
WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone :- 22878 Nigeria, (Ọja
ATI NI ṢỌBU
Ẹ-OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN.

# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA*

No [illegible] TUESDAY DECEMBER 8, 1964 (2D)


## Abubakar Lọ Fi Okuta Ile Iwosan Unifasiti LeLẹ

IDI-ARABA:- Ni ọjọ Alamẹta ti iṣe ọjọ karun Oṣu yi ni Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lọ fi okuta ile Iwoan titun ti ilẹ ẹkọ giga julọ ti Unifasiti ti ilu Eko le ẹ ni ibi ti ile iwosan na wa tẹlẹ ni Idi-Araba, Surulere ni deede agogo marun irọlẹ ọjọ karun Oṣu yi.

Ninu ọrọ Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Alhaji Abubakar fi ye awọn enia ilẹ Naijiria ati awọn Alejo lati ilẹ okere ti nwon fi iwe pe sibi ẹyẹ ifi okuta ile iwosan na lelẹ pe ohun to jẹ pataki julọ ninu ifi okuta ile iwosan yi lelẹ ni gẹgebi ilọsiwaju ati ẹmi gigun larin awọn enia ilẹ Naijiria ati pe a ko gbọdọ fi oju pa eto ilera awọn enia rẹ rara

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye pe ti awon enia ilẹ Naijiria ba si nfẹ lati ni ilọsiwaju o ni eto ilosiwaju na ni lati wa pẹlu gẹgebi ilu ni lati gbodo ti daju pẹlu awon omo ti awon enia ilẹ Naijiria bi si ilẹ Naijiria pẹlu eto ilera ati itoju ara to daju pupo larin awon enia ilẹ Naijiria.

# Ipinlẹ Iwọ Orun Bọ Ṣinu Aiye Rere

### Lati Oju Ewe Kiní

akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lasiko na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria si ṣe alaye pe ipo to jẹ pe o tobi pupọ ju fun ẹgbẹ Alatako ninu Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun nigbana ni nwọn sọ pe Ologbe Alhaji Adegoke Adelabu ni awọn fun ni ipo Olori Alatako lasiko na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye pe lasiko ti nwọn gbe ofin pajawiri wọ ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ẹgbẹ ilọsiwaju tun ṣe alaye pe ẹgbẹ Alakukọ si lo ipo wọn rere lati yan ọkan ninu ọmọ ilu Ibadan gẹgẹbi ọkan ninu awọn Aṣoju labẹ Alakoso eto Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lasiko na eyi ti iṣe Dokita Moses Adekoye Majẹkodunmi.

Awọn ẹgbẹ na si tun fi ye wa ninu irohin wọn pe Ọkunrin ti nwọn mu silẹ ṣalo si jẹ pe nwọn fi iya jẹ pupọ lasiko to si wa ni ile iṣẹ ti Ijọba ibilẹ ilu Ibadan nitori pe o si jẹ ọkan ninu awọn to jẹ ọre Ologbe Adegoke Adelabu lasiko ti o wa laiye.

Awọn ọmọ ẹgbe ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA tun ṣe alaye pe nitori pe ija kan wa larin awọn ọmọ ẹgbe Alakukọ ti ilu Ibadan lasiko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapa Ijọba ilẹ Naijiria ninu ọdun 1959 eyi to jẹ pe awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ mẹfa to gbe apoti ibo sile lafi ara mọ ẹgbe Oṣelu kankan eyi ti awọn ọmọ ẹgbẹ na mẹfa si fi wọle ti nwọn si lọ parapọ mọ ẹgbe Ọlomi NPC. Awọn ọmọ ẹgbẹ na si ṣe alaye pe nkan ti o jẹ ki ẹgbe Ọlomi NPC yan Mallam Lawa gẹgebi Minisita kekere fun apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ninu apapọ Ijọba te fẹ pari bayi.

Awọn ọmọ ẹgbe ilọsiwaju ile Naijiria UPGA tun kesi Oloye Akintola pe to ba fẹ ṣe iwadi nkankanpe kio lọ ma bere lọwọ Ọga titun ti nwọn ṣẹṣẹ jijọ papọ lati bere idi rẹ ti ko fi yan Ọgbẹni Richard Akinjide to jẹ pe on lo wa lọdọ wọn to si jẹ ẹnikanna gẹgẹbi Agbẹjọro ki nwọn si yan gẹgẹbi Minista ni ọdọ wọn lọhun,

### ẸYẸ

Ẹgbẹ ilosiwaju ilẹ Naijiria tun ṣe alaye pe ẹgbẹ Alakukọ si tun lẹnu lati fi sọrọ lori nkan ti nwọn sẹ fun ilu Ibadan fun igba die ti ẹgbẹ Alakukọ si fi wa ninu akoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu ọdun 1963.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye pe ẹgbẹ Alakukọ iba gbinyanju lati sa agbara ti nwọn ni fun awọn enia ilu Ibadan ati paapa fun ẹyẹ to yẹ ki nwọn ṣe fun awọn enia na lori iru ọmọ ilẹ Ibadan bi iru Ologbe Alhaji Adegoke Adelabi eyi ti ẹgbẹ na ṣe alaye pe nwọn ko si ṣe ọna to tọ fun enia ilu na.

Ṣugbọn awọn ẹgbẹ ilosiwaju ilẹ Naijiria si ṣe alaye pe awọn fun awọn enia ilu Ibadan ni idaniloju pe ti ẹgbẹ ilosiwaju ile Najiria ba le gba akoso Ijọba apapo ile Naijiria nwọn awọn yio si ri pe ẹgbẹ ilosiwaju yio si jẹ ki ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bọ sinu aiye rere.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye pe kini Oloye Akintọla ṣe si awọn enia ilu Ibadan ati pe on kanna lo ge ilu Ibadan ku si gẹgẹbi o ṣe na tẹlẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ ilọsiwaju ilẹ Naijiria tun ṣe alaye pe fun igbẹkẹle ti Olori



Alhaji Aminu Kano

ẹgbẹ Afẹnifẹre Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni si awọn enia ilu Ibadan nwọn ni o kọ ile si ilu Ibadan. Awon ọmọ ẹgbẹ na si tun ṣe alaye pe kini ẹniti o gba ipo rẹ lẹhin ti o fi ipo rẹ sile gẹgẹbi Olotu Ijoba ipinlẹ Iwọ Orun ilẹ Naijiria ṣe o le jẹ ohun akọsilẹ fun awọn enia lati ma ri.

Awọn ọmọ ẹgbe ilọsiwaju ilẹ Naijiria UPGA tun sọ pe fun iwa ikorira ti Oloye Akintola ni si awọn enia ilu Ibadan ni ko ṣe kọ ile si ilu Ibadan ati pe iru ile to yẹ ki o ko si ilu na pe ilu rẹ lo si nṣe ogo na si Awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA tun ṣe alaye pe Oloye Akintọla si ka ara rẹ gẹgebi Alejo fun Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Awọn ọmọ egbe ilosiwaju ile Naijiria UPGA si tun ṣe ileri pe eniti ko ni nkan kan ni ilu kan ni nwọn si sọ pe ko bikita ti gbogbo ilu na ba fẹ parun nigbati ko ni nkankan to jẹ pe yio si padanu ninu ilu na.

Ẹgbẹ ilosiwajn ile Naijiria UPGA si ṣe alaye pe awọn si fun enia ilu Ibadan ni idaniloju paapa julọ awọn enia ipinlẹ Iwọ Orun pe ki nwọn ma ṣe iye meji ati pe gbogbo bi ilọsiwaju yio ṣe fi wa ni ipinle na ni egbẹ wọn yio ṣe lẹhin ti nwọn ba ti bori ibo na nti pe ki nwọn ma ṣe fi eti si gbogbo irọ ti Oloye Akintọla npa fun wọn bi ko ṣe pe ki nwọn kọ silẹ pẹlu awọn ọmọ egbẹ re ti nwọn yio si dibo fun losiko idibo ti ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ile Naijiria to mbọ yi.


## Ipolowo Ọja Rẹ Ko Tẹ Yege

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO ỌJA RẸ SINU

**IROHIN IMỌLẸ**

T'ODUN KA FUN GBOGBO YORUBA

KOWE IPOLOWO OJA RE SI
ADVERTISEMENT MANAGER

**IROHIN IMOLE**

16, Bamgbose Street Phone 219-5



Printed And Published by Modupe Printing Press, 16 Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Acting Editor: (Adele Olotu) 'BAYỌ TIAMIYU 26, Ọjinidudun Street Lagos (8/12/64)